# Bi aṣen ṣe Aluwala olomi, ati Aluwala oni yẹpẹ, ati iwẹ

2

## Bi aṣen ṣe Aluwala olomi.

Ama da aniyan aluwala pẹlu ọkan, lẹhinna ao sọpe: Bismillah, lẹhinna ao wẹ ọwọ wa mejeeji.



1

Lẹyin naa ao fi ọwọ ọtun bu omi sẹnu, ao fi yọ ẹnu wa daada, lẹyin naa ao tu danu, lẹyin naa ao fin omi simu, ao si fin sita nipasẹ gbigbe ika ilabẹ ọwọ osi ati atanpako si ori imu wa.



2

Lẹ́yìn náà, aó fọ ojú wa ˝láti ibí irun waju ori títí dé ìpẹ̀kun irùngbọ̀n àti àgbọ̀n, ní gígùn, àti aarín etí mejeji ni fífẹ.˝



3

Lẹ́yin naa ao fọ ọwọ wa lati ori ọmọnika titi de igunpa, ao bẹrẹ pelu ọwọ ọtun, lẹhinna osi.



4

Leyin naa ao fi omi pa gbogbo ori wa, ao fi ọwọ pa lati iwaju ori lọsi ipakọ, leyin naa ao da ọwọ naa pada si iwaju ori wa.



5

Lẹ́yìn náà, aó fi ìka ilabẹ wa mejeeji si inu etí wa mejeeji, áo sìfi àtà pàkò pa ẹ̀yìn eti naa.



6

Leyin naa ao wẹ ẹsẹ wa mejeeji pelu awọn kokosẹ.



7

Idajọ kikọja ala ti Ọlọhun e lofin?

Ko lẹtọ kia kọja ala ti a ṣe lofin ninu aluwala, gẹgẹ bi ki a wẹ ju ẹmẹta lọ, tabi ki a wẹ ọwọ kọja igunpa, tabi kia wẹ ẹsẹ kọja kokosẹ, tabi kia fi omi pa ọrun.



8

Tia ba pari Aluwala, ao sọ bayi wipé:"Ash'adu anla ilaaha illa Allah wahdahu la shariika lahu, wa ash'adu an'na Muhammadan 'abduhu warasuluhu", Ninu Hadeeth ti Tirmizi gbawa – "Allahumma ij'alni mina tawwabeen waj'alni minal mutatohireen".

9

Ninu awọn nkan ti onba aluwala jẹ :

1- Awọn nkan ton jade lati oju ara, gẹgẹbi itọ, tabi igbẹ, tabi iso.

2- Yiyẹ ilaakaye nipasẹ sisun tabi didaku.

3- Jijẹ ẹran rakunmi.

10

## Bi aṣen ṣe Aluwala oni yẹpẹ

Aluwala oni yẹpẹ: irọpo lojẹ fun aluwala olomi ti ko ba ee e lati lo omi fun awọn orikerike ara tabi apa kan ninu rẹ, nitori aisi omi, tabi ibẹru ipalara nipasẹ lilo omi, ao fi iyẹpẹ rọpo omi nio.

1

Ao da aniyan pẹlu ọkan wa, lẹyin naa a o sọpe: Bismillah, lẹyin naa, a o fi ọwọ lulẹ lẹkan, a o si fi ọwọ naa pa oju wa ati ẹyin ọwọ wa.

1 2 3 4



2

A ko ṣe lofin lati fẹẹ awọn ọmọnika nigba ti aban fi ọwọ lu iyẹpẹ, bakan naa a ko ṣe lofin pe ki a ti ika ọwọ bọnu ara won ti aban fi ọwọ mejeji pa ara won.



3

## Bi aṣen wẹwẹ ọranyan

Ao da aniyan pẹlu ọkan, a o si sọpe: "Bismillah" ni bon kẹlẹ, lẹyin naa, a o fi omi wẹ gbogbo ara wa titi de gbogbo abẹ awọn irun wa, ao si fi omi yọ ẹnu wa, ao si fin omi si imu bakan naa.

1

- Awọn nkan tin sọ iwẹ di ọran yan :

1- Janaabah: Ti atọ ba jade lara nipasẹ ibalopọ tabi nkan mi, tabi ipade abẹ akọ ati abọ. 2- Jijade ẹjẹ nkan o u ati ẹjẹ ẹyin ibimọ. 3- Iku ti kin e iku ẹhiidi. 4- Wiwọnu Islam keferi

2

ẹniti opese akọsilẹ yi ni : Dọkita Haitham Sarhan, olukọ ni Mọsalasi Anabi ati alamojuto "Mahadu Sunnah: mahadsunnah.com"